Chief Secretary to the Government


# EKO AKETE.

"Emi yio fi ohun ti o ndun Makunnu han awon Alagbara, Ngo si je Alagbawi awon Odi."—W. T. Stead

Vol. VI. No. 301 Saturday, November 17 1928 4d

The Leading Weekly Vernacular Newspaper in Nigeria.



22 NOV. 1928



## White's Radical Gonkiller.

:o:

(NATIVE.)

[ *A complete cure for old and fresh Gonorrhoea.* ]

When Gonorrhea is not properly cured, it gives rise to other troubles and diseases such as Barreness, Piles, Kidney Diseases, Stricture, Rupture, Rheumatism, Sore-eyes, etc.

N.B.—This Medicine cures Gonorrhea completely in either man or woman, so that no secondary diseases can follow.

Made from pure **Native Herbs,** and sold only by

VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist.*

41, Offin Road, Lagos.

PRICE: Ten Shillings (10/-) per bottle.

*Packing and Postage 2/6d. extra, to all parts of Nigeria.*

## EGBOGI ALAWOTAN ATỌSI.

:o:

[ *Fun Atọsi lailai ati titun.* ]

Ti a ko ba tete wo Atọsi san daradara, o ma ndi enia lọwọ lati ṣe abiamọ, o si ma nfa oriṣi arun mi wa, bi:—Jẹdi-jẹdi, Aran, Iju, Ẹda, Ipake, Ase, Lakuregbe, Arun Oju, ati arun mi.

N.B.—Egbogi yi nwo Atọsi san lawotan patapata, ko si njẹ ki o ri aye wu arun mi silẹ.


LOOK FOR
THE PORTRAIT
OF
D. Earl Sloan
SLOAN'S
N & B
FAMILY
LINIMENT
Trade Mark Registered
KILLS PAIN
mists and Patent Medicine Dealers
Carton adopted 1916.
s for Great Britain
FASSETT & JOHNSON,
Road, London, E.C.
RED ONLY BY
CORPORATED )
ST. LOUIS. TORONTO, CAN.
ome Office. BOSTON
in United States of America
RELIEVES
Rheumatism
Neuralgia
Sciatica
Sore Gums
Sore Muscles
Sprains
Strains
Swelling
Tender Feet
Toothache
Stiffness and
Severe
Keep away from
Fire or Flame
TO
STOP YOUR
ACHES & PAINS
SIMPLY USE
SLOAN'S LINIMENT
Sold by all Dealers.
Wholesale Fassett & Johnson Ltd
Clerkenwell Rd London.
England

*Editor & Proprietor:—*
ADEOYE DENIGA,
*Office* 24, Williams Street,
Lagos, Nigeria.

**ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ**

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oşu mẹfa | 6/- | 6/6d | 7/- |
| Oşu mẹta | 3/- | 3/6d | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranşẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

ARA ILỌRIN MESUJAMBA.

Igida ni iwa areke-nda pupọ ninu awọn Alagbe Eko; irohin kan kan ni ni Satide ijẹjọ pe o jẹ aşa ara Ilọrin kan ti o nşagbe kakiri igboro Eko lati ma da şile meji meji ojumọ ni ese si ọwọ iya-ọlọka kan ti o si nko esu na ti o ba di ipari oşu a gbọ pe ti o ba di alẹ ara Ilọrin yi a gbe ẹwu akisa jinwinni k'ọrun to si fi ori pa oju rẹ eyiti o ma ndi pinpin, a si bẹrẹ si fi igi ta rara ojuọna a ma şeti afọju a si ma şe agbe kiri ilu, ni ona bayi a gbọ pe o ni iye owo ni kọbọ kọbọ ati idaji kọbọ ti o nri gba lọ si ibiti o gbe ogbe ninu rẹ ni o ti nri esu şile meji meji da; ti o ba si di oju osan, a sope o jẹ aşarẹ lati wẹ ki o si wọ aşọ ti o mọ́ lori, a si gbọ pe kiko lati ma pe awọn ero ti o nlọ t'o mbọ! ni gasikiya, Eko gb'ole o gb'ọlẹ.

DUNIYAN—LABARI.

[ LATI ỌWỌ KEKERE-AWO. ]

IGBA IYAWO MBỌ.

Aseko de gbẹrẹ fun awọn Imale lati ma gbẹ iyawo won. Nitoripe ibi ti nwọn ngbe iyawo ti a şe alabapade larin ọsẹ to kọja ko ni iye anu şe wa wa diẹ lati sọ wipe boya ni igbeyawo ọdun ni yio larinrin, ohun kini ti a fi sọ bẹ ni wipe ofọ pọ lodẹ ekeji o tun gbe ibẹ owo ko si lode tobẹ.

ỌDUN MBỌ.

Nkan mbẹ ni ilu yi ti a ko i fẹ bikita fun, bẹ bi o ti wu ki o ri bẹbẹkubẹ ibe lo mbọ, iyẹn ni wipe eyi ti a ko i fẹ bi ita fun ni a o ma mu şe bi o ba ya, Ọlọrun ma jẹki o le ju bẹ lo, ohun ti o mu wa sọ bẹ hi wipe, ọdun Keresimesi nsure bọ, fikanfi-kan, o ku oşu kan pẹlu ọjọ mele kan, sibẹsibẹ a ko gbọ kuku-kẹkẹ tobẹ, o şe ! nkan mbẹ !!

OFIN MELO LO MBẸ?

Nnu ofin mẹwa ti Oluwa sọkalẹ wa fun Mose tabi Anabi Musa—ọkan ninu rẹ ni wipe iwọ ko gbọdọ pania, a si ri wipe ofin kan yi wuwo julọ bi a ba ni ki a gbe gbogbo wọn si ori iwọn iwọ ti o npe 'ra rẹ ni oşo tabi ajẹ, ti o nşe jambu ọmọ ẹnikeji rẹ, nibo lo ma ru u wo lọjọ *Ajinde* tabi *Aliqiyaomat*?

SIMEON JACOBS.

Gbukẹ li a gbọ ti ofo alagba Simeon Jacobs, ni owurọ ọjọ *Monday* ijẹfa, nwọn gbe o u rẹ lọ si Şọşọ Olowogbowo fun isin ikẹhin rẹ, lati ibẹ lọ si Ikoyi, a ki Lọya Desalu ti wa ati awọn oloku yoku, Oluwa ko gbe baba si afẹfẹ rere—amin.

KẸLẸKẸLẸ O!

A fi eyi şe ikilọ fun awọn ẹniti o ma ns ba nwọ de oru ki nwọn şe kẹlẹkẹlẹ d'ọwọ njiti fun aseko yi, ode ti a wa yi dara ju ti a ko gbọdọ wi nkan miran, ki Ọlọrun fi işọ Rẹ şọ olukuluku.

IGIDA!!

A gbọ wipe gbirihan ni okunrin kan ku si apa adugbo kan ni ọjọ ọsẹ ti o kọja yi, ti gbogbo ẹnikẹni si nlọ wo o, bi eyi ba jẹ bẹ, ko ha yẹ ki a sorikodo bayi ?—eyi ki !

(YOUNGMEN XTIAN GUILD.)

Awọn Ẹgbẹ (Youngmen Xtian Guild) lọ ba Iya-ẹgbe wọn şe ajọyọ kan ni ọjọ Satide ijẹjọ ni ojọ kẹwa oşu yi (10.11.28.) ni No. 12 Dention Street, Ebute Mẹta, Madam Araba Taylor, Iya Ẹgbẹ şe ohun ara lọjọ yi, ko si botiri ni ti ọjọ na, ko si ohun ti ko pe nibẹ ni ọjọ na, iru ere wo lo ma şe ti o ko ni ba ni ile Iya-ẹgbe, Madam Araba Taylor, apọn bepọrẹ obinrin to tutu bi ọsun ẹlẹyinju ẹgẹ, afifẹtẹ-oko lọrun, a r mi de lo, obinrin rọgbodo, binrin rodorodo bi olu gan, egan loku awa ngba fun nyin o, wara were to ko kọko de ibi ti a wa yi orişirişi (ganre) ni nwọn ko kalẹ fun wa, lati ma fi şe idaraya lape awọn ti nwọn ma şere *ball* de ba wa nibẹ gbogbo re ndun yungba, lẹhin eyi ni nwọn wa bẹrẹ si ma fun awọn enia ni orişirişi ohun jijẹ ati mimu, orişirişi keki buredi miliki jolọfu rice, gbogbo rẹ pe patapata lẹhin na,

a wa bẹrẹ si ọti mimu kini ohun ti o fẹ mu, iru ọti wo ni ko pe nile Iya-ẹgbẹ, apọn beporẹ, bi Gin Lẹmọledi, Beer Rum, Wine, to ba si wipe ninu gbogbo awon ti a daru'kọ yi ko tẹ ẹ lọrun Wishiky nkọ o. Alamu yagbẹ, lẹhin na Ẹmu *palm wine* nigbana ni ijo tun bẹrẹ ti awọn odomokunrin wa tọ sode o pẹlu awọn awẹlẹwa ẹlẹyinju ẹgẹ kini o tileku bi o ba majo rara a jẹ pe o wa si ile Madam Araba Taylor nitori ọti olojeloju yio ran ẹ ni iṣẹ to ko ni le jẹ.

Bi iwọ papa ko t lẹ fẹ jo arara nigbati o ba ri oju Iya-ẹgbẹ ẹlẹrin ẹyẹ, obinrin bi ọkunrin sink-inrinmini afin ai mo ni, a ke ni mọra Iya-ẹgbẹ, a bi wa gbedọ bi a ko Ṣebe agbadun rẹ o. Awon enia pataki-pataki ti o wa si bi apejẹ na ni wọnyi, a o daruko diẹ fun min ninu won, awọn bi Ogbẹni J. H. G. Willoughby. Ogbẹni Oke Adeshigbin, Ọgbẹni Henry Willoughby, A. A. Ẹnloh, M. A S. Ab n, O. A. Coker, A Ọlaiya J. O. Abiola, O. M. Coker, E. O. Daniel, D. O. Martins, J. A. Thompson, G. I, Vicent, A. O. Vicent, A. N. Adeniyi, awọn diẹ ti a le da orukọ wọn fun nyin ni yi nitori enia ti pọju ko si aye to lati da oruko awọn jakanjakan to ku o ku diẹ ki o mọ ẹniti o tu on ni ọjọ yi. Iya ẹgbẹ wa ko ni tete ku, ẹniti o gbere pe ki o ku ko ni ku-re, Iya ẹgbẹ wa ko ni tete ku o.

Lẹhin ti a kuro nibẹ tan ni a tun tọ Ọgbẹni kan lọ; Mr. Awolaja ẹniti a bo pe o nsin oku iya rẹ ni Ebute Mẹta nibẹ, iyoku di regbe atupa oni-kabaidi ni Ọgbẹni yi fi wakati kan ati abọ ṣe titi a fi kuro nibẹ igi ma da o bi olonjẹ gbe ri wa sa, a fi ai jẹ tẹ.

---

A ki awọn ẹbi Pa J bowu, nwọn ku afẹku, iku baba wọn ẹniti a gbọ wipe o fi ọmọ bi metadin-logun s lẹ l, nipa eyi l ju ti wa, o tẹle Bibeli to wipe ẹ m bi si i ẹ si ma resi. A si tun ki awọn Loya Baptist nwọn ku afẹku ti Mammy wọn, a tun ki awọn ẹbi Nottidge ti Mammy, a si tun wa ki Loya Desalu ti Baba-baba rẹ, fun gbogbo awọn ẹni wa mẹrin wọnyi—sun re. Ninu ọsẹ y, ojojo nṣe-ogun ara ogun kole, nitorina, gbogbo ọrọ wa di ọsẹ to mbọ.

---

Bi a ba ngbọ irohin awọn Ọba wa alade, inu wa ma ndun bi gbogbo enia wa ba nsọ wipe ọba bayi l ayi lo ṣe fun wa inu wa ndun. Ọrẹ wa J. Ade. K. Williams rohin fun wa wipe His Royal Highness Dagbarewe of Idowa ṣe ni alejo, o si fun ni iyẹsi eyi to t ati eyi to yẹ, awọn akọwe rẹ ati iranṣẹ papa eyi ti wọn ṣe ko kẹrẹ, nipa bayi inu wa dun nipa iwa mimọ iyi enia ti Dagbarewe hu fun ọrẹ wa yi, nitorina adura wa nipe ade a mọ ri, bata pẹ ni ẹsẹ—aṣẹ.

## ARUN NI MU NI JẸUN ỌTA ẸNI, ỌLỌRUN MAJẸ KA RI ARUN."

Ni ọsẹ melo sẹhin mo gbe ẹnu le ọrọ ohun to nbẹ ni ode Eko loni, mo si fi gbogbo ọrọ lukuluku yi le awọn Alufa ti Ṣọṣi, ti Maṣalaṣi, lọwọ wipe ki wọn tẹwọ gba Adura, ṣugbọn lẹhin na, mo ri wipe arun yi ngadagba si, sibẹ-sibẹ pi-i-i bi ẹni pana, bi npa enia, ko sin din ku atari, ninu ile miran larin ọsẹ kan, ọkunrin gende meji ati obinrin aghalagba kan lo mu lọ, ni adugbo miran larin oṣu kan, iye ẹniti omu lọ ju mewa lo, bẹni ọpọl po awọn eni wonyi, ni awọn alaṣẹ ti fina-fina si ile won, bi igbati awọn ara Tọgbẹ nyan ẹja ni atan, bakanna ni nipa wi wọn omi sile ati i ipa bi bu nkan olo-run sile, wọn bu gbogbo rẹ si ṣugbọn pibo, nje mo wa bere, ko si ọna miran ti nkan yi file buku, ẹlomiran ko si nkankan to ṣe, boya enikan ku ninu ile rẹ, nipa bẹ wọn a bu apa fun, ki ṣe bubu apa ni mo fẹ sọ, bikoṣe gigun apa, boya ẹniti wọn gun apa fun yi, aiperi wa ni ara rẹ, nipa bẹ otutu yio gbe ṣanlẹ, osi le ba bẹ lọ, nkan keji ẹwẹ, ẹlomiran ko fẹ otutu lati kekere rẹ wa, bi wọn ba s ko won lọ si Ikoyi, inu otutu lo nlọ gbe, bẹ i bi otutu ba nmu ju, Temperature rẹ yio g, nipa bẹ awọn Ijọba yio sọ wipe arun yi ti ran, ni asiko yi, awa ko mọ iyato larin ewo, balọ, yato si arun ode yi, bi Balọ tabi Ewo wu si ẹnikan lara, awọn olotu ilu ọga fa oluwa rẹ ti di gbigbe lọ, nje mo bere nkan wọnyi ko le ṣe eni mọ n? Ni ọdun kerin ọhun, nigbati arun yi bẹrẹ ni Oko-awo, ni ile Gogobiri, ọpọlọpọ wa ri a nsọ wipe, Oko-awo nrun pupọ, ẹrẹ, ogodo, ẹgbin, ohun ẹ, lo pa pọju ni adugbo yi, ohun lo jẹ ki arun yi ko burekẹ—burekẹ sibẹ, nje mo bere iwọ to mọ Sanitation ti ti ile tẹ mọ toni-toni nko, Plague ko bẹ ile rẹ ninu ọdun ni. Mo bẹ ẹyin aṣoju wa ni Igbimọ Muni-siba tabi ti aṣofin, kẹ bawa bere lọwọ awọn olo'a ilu wọn yi, bi ko si ọna miran ti a le gbe oro na gba, ti ko ni si iku pupo ba wọnyi m? Eyi ṣ npapọju ninu ọdun ni, ko si ohun ti mo ma wi ju wipe ki awọn ẹniti wọn mọ oruko Olọrun pe ni ọna to wun ko jẹ ki won j ki wọn ba wa pe, ki Ọlọrun le ṣ ju anu rẹ wo ilu wa yi, ni asiko diẹ to ku ki ọdun yi pari Amin.

## Ẹ KU IRỌJU. Ẹ KU ARA MIMU LE

Aki awọn ẹbi ologbe Ellen Caroline Eluyemi Taiwo Adegun ti wọn jade ni Ṣọṣi Olowogbowo ni Sunday to kọja, ati awọn ẹbi ọkọ l tun-lo l wọn ku afẹku, Ọlọrun ko fi ran mo bẹ. Ki ama ri esi ko yi ano. Olọrun ko si tu iya olo-be yi ninu, eniti ẹ mọ meji sun ni owọ rẹ ni arin ọsẹ kan ra Ni ọsẹ ọla, ni awọn ẹbi kan ra ni wọn o jade ni Ṣọṣi U. N. A ni ẹgbẹ ti Dokita Ṣapara nipa ti Ezekiel Ẹun Akiwande aburo ologbe Mrs. Adegun. Oluwa ko gbe awọn mejeji si afẹfẹ rere.

Emi ni ti nyin nitotọ,

ENIA KO DA BI ALLAH

## IROHIN AWỌN IPILẸṢẸ ISIN IGBAGBỌ.

Mo juba o ẹnyin Agbalagba Ọlọla-nlajulọ,

Mo fẹ sọ diẹ nipa Itan Isin Igbagbọ eyiti mo gbọ ni ẹnu Baba mi nipa ti Ọlọrun. Awọn ti wọn ba Ọlọrun rin nipa Isin Igbagbọ awọn Ọlọla-nla Messrs. J. Bọla, Oshodake, Showẹmimo, D. Okunlaja, J. Awolaja, Adetẹnbi, P. Shogunlẹ, Shoderu, G. Adelu, J. Ọpẹbi, Oduyebọ, J Sholu, P. Ọrẹjupe, G. Ọshinuga Ogunuyi, J. Adesanya, Shadare, Owolaja, Ifagbemi, Oyegunṣẹn, Young.

Awọn diẹ ninu awọn Ọlọla-nla ti Ọlọla-nlajulọ GOMINA GLOVER tọrọ Ilẹ Ilu Ebute-Mẹta fun ni yẹn ko to wa bere ni ọwọ wọn pe ki on lọ mu owo wa fun nyin ni tabi ewo ni ẹnyin nṣe ni iṣẹ awọn Onigbagbọ dahun wipe oko ni awọn nfẹ ro, nigbana ni Ọlọla GOMINA GLOVER dide ti o wa si Onigbongbo ti o tọrọ oko ni ọwọ ara Ikẹja ati ni ọwọ ara Onigbongbo fun wọn, nigbati wọn ni oko tan gbogbo awọn Onigbagbọ wọn pejọ won ṣe dehun wipe Ofin kini wọn ni a ko gbọdọ fẹ obirin ara wa nibi ni Onigbagbọ ara ẹni o, wọn ni ẹniti o ba ru ofin a o nọ ni ẹgba a o le lọ. Ofin keji wọn ni a ko gbọdọ ja ara wa ni ole, wọn ni ẹnikẹni ti o ba ja ole awọn a nọ, wọn a si le lọ. Ofin kẹta won ni ẹnikẹni ko gbọdọ ṣe ogun buburu rara ninu awọn, bi a ba ri ẹniti o ṣe ogun buburu awọn a nọ wọn o si tun le lọ. Ofin ẹkẹrin wọn ni ẹnikẹni ninu awọn ko gbọdọ gba obirin ara Onigbongbo ati obirin ara Ikeja ati obirin ara Ọrẹgun, wọn ni a le fẹ ọmọ won iyẹn dara o, ẹnikẹni ti o ba gba obirin wọn, wọn sọ pe ko ni ṣ' anfani fun oni yẹn o. Wọn ko jẹki awọn Ofin na bajẹ ni oju wọn ni igba laelae ri, nitorina o yẹ ki a ranti wọn ninu adura wa Ki Ọlọrun jọwọ ṣanu fun gbogbo awọn Ọlọla-nla yi, Amin. A fi ẹnikan ṣoṣo ni o jẹ enia-kenia tabi enia-buburu ninu awọn ọmọ ti won bi si oko Onigbagbọ nisisiyi Alejo ko gbọdọ mu Obirin ti o ni ẹwa lọ si arin won, a ni le gba patapata ko jẹki Irẹpọ wa larin ọkọ ati aya rara yio rukerudo silẹ larin wọn, itẹ gbigbona si wa si gbo bo enia ninu ọkan rẹ lo wa kẹni ma ni o wa ni ọkan rẹ o si jẹ Alagabagebe enia nitorina ẹ jọwọ ẹ ba wa tọrọ adura ni ọkan mimọ fun iru enia bayi "Ki Ọlọrun jọwọ ba wa yo gbogbo ero buburu, ero agabagebe kuro ni ọkan rẹ, ki o ma ko ba awọn enia rere ti o kun ni oko Onigbagbọ ki wọn ma le ba Ofin ti Baba wọn ti ṣe silẹ jẹ nitori ọjọ Idajọ ọjọ Ẹru."

Ki Ọlọrun jọwọ ṣanu, ki o t' ilẹkun buburu fun wa, ki o si ṣ' ilẹkun rere fun wa.

Emi ni tiyin nitotọ,

J. A. O. SHOMADE.


## *KERE O!*

OYINBO KESSLER GBE TANA DANU, O GBE ...I DE.

Irin-iṣẹ Gbẹna-gbẹna to dara ju ti nwọn ti nlo fun iwọn adọta ọdun sẹhin wa fun tita ni Ṣọbu ***Kessler.***







Ẹ ba mi lọ si Ṣabu na, ẹ o ri ti nyin yan nibẹ, ọpọlọpọ ọkọ ni owo rẹ, iba diẹ ni o wa. Aworan Irin-iṣẹ wọnyi ni a ya sinu iwe yi fun nyin yi. Lọgan lẹ o ri ra.

Ẹ lọ yan ti nyin ni Ṣabu Oyinbo KESSLER ni No. 7, Labinjo Lane, ni Eko.







Ẹnyin ara Eko., ara Oke ati ilu miran, gbangba dẹkun, kedere bẹwo, Ṣabu Kessler ti kuro ni mori nkan firi irohin ko to afojuba. Ẹ ma ṣe gbẹhin ki ẹ to ra ti nyin, ki ẹ ma ba joku Ologbo.

## IWA AGABA-GEBE AWỌN ỌMỌ ANABI ADAMỌ.

Si Oniwe Irohin *Eko Akete.*

Ninu iwe "Eko-akete ti ọjọ kẹsan oṣu June to kọja yi, nibẹ li a gbe ti fi oro wa ti nipiṣẹ "nwọn nge nyin lọwọ, ẹ nbọ oruka" ti a mba bọ ri, aye ko si si fun wa lati igba na lati mu paṣamọ ọrọ na nṣọ, ṣugbọn loni a o tun bẹrẹ si gbiyanju awọn ọrọ na, gẹgẹbi atẹhin wa.

Ọrọ titun ti a o tun mu sọ ni ọrọ ti a fi si oke ọrọ iwe wa yi, a ti mọ wipe oniṣe ko ni fi iṣe rẹ silẹ, ni ti awọn ẹniti awọn ọrọ wa le mu ba wi, ṣugbọn sibẹsibẹ awa ko bikita lati ma ba iṣẹ wa bọ, boya nipa bayi, a le ma ri awọn ẹniti o le ma ṣe ironupiwada kuro ninu awọn iwa baun, ko si ẹniti Oluwa nfẹ lati gbe sọnu, awọn ọmọ Anabi Adamọ fun 'rawọn ni wọn ngbe ara wọn sọnu, nipa wipe ki a ma ṣe arawa ni iranti ọrọ tabi ofin Ọlọrun ki a si ma ṣe eti gbọnin si i.

Ki ato bẹrẹ si ọrọ mi, o yẹ ki a bere bi gbolohun melo kan lọwọ arawa, pipa lọwọ Imale ati lowọ Kiriyo, ibere na ni wipe kini igbagbọ ti a ni si Ọlọrun ti ẹ ni on lo yẹ lati ma sin I?

Mo ṣe bi Kiriyo ati Imale lo ma nṣe iwasu kakiri fun ni wipe iwọ ko gbọdọ ni Ọlọrun miran pelu emi, iwọ ko gbọdọ jale, iwọ ko gbọdọ pa enia, iwọ ko gbodo jẹri eke si ọmọ ẹnikeji rẹ, bẹni iwọ ko gbodọ ṣe panṣaga tabi agbere, ki lo ha ṣe ti o jẹ wipe awon elomiran ki ibikita fun awọn ofin wọnyi lati ma pamọ?

Ni toto a le ma sọ ri tabi nigbagbo wipe awọn aborișa ti a mọ ni keferi ko ni wọ Ijọba ọrun ni ibiti awọn Musulumi npe ni *Alijanal* nitori wipe nwọn nya erekere tabi nwọn npe orișa ni Ọlọrun tiwọn, lọna iyẹn nwọn le jiya lọjọ idajọ ṣugbọn sibẹsibẹ o yẹ ki a mọ wipe a ki yio ṣai ri ninu wọn ti yio de Ijọba ọrun, gẹgẹ bi iṣẹ miran ti nwọn nṣe ti awọn ọpọlọpọ Kiriyo ati Imale miran ki nṣe, bi iru iṣẹ wo? nwọn nsa fun gbogbo ofin Oluwa, ṣugbọn Ọlọrun ti nwọn ki nsin nikan lo mu iyatọ rẹ wa.

(*Koi ti pari.*)

ỌMỌ-ILU.

---

## KILO NMU ABIKU WA?

Ọkan ninu ohun ti a gbagbọ daindain ni pe Ọlọrun ni Ẹlẹda ohun gbogbo ti a ri ati eyiti a ko ri. Ṣugbọn bi o ti jẹ pe ibukubu li a fi enu bu ohun ti a ko ba ri, ọpọlọpọ iyan jija lo wa niti awọn nkan be... mo daju pe Ọlọrun da awọn enia,—ṣugbọn ... awọn ... ti ṣe jẹ ẹmi rere ti awọn kan si jẹ buburu ni ohun ti a ko le mọ lode aye. A mọ daju pe awọn ẹmi rere wọnni nṣe iranṣẹ fun Ọlọrun, ati pe awọn buburu nṣe iranṣẹ fun eṣu,—ṣugbọn bawo ni awọn ẹmi wọnyi (iba ṣe rere tabi buburu) ti ba ẹmi ti enia tun si, tabi li ọna wo li awọn ati enia farakọra? Tabi agbara wo ni a fun wọn lori enia,—gbogbo iwọnyi lo jẹ ohun ti a ki yio le mọ idi rẹ bi o ti wu ki a wa a to nihin.

Ọrọ Ọlọrun ti nṣi gbogbo ohun ọrun paya fun ni ko ka iwọnyi si ohun to yẹ daindain fun igbala araiye, nitorina ko ṣi nkan wọnyi paya fun awa enia; o wa ku ọgbọn olukuluku orilẹ-ede lati ma dari won. Ẹ je ka kiyesi pe larin awọn orilẹ-ede ti ko gbọ ọrọ Ọlọrun, agbara ti nwọn fi fun awọn ẹmi pọju bi o ti yẹ, o fẹrẹ dabi ẹnipe nwọn ko ni ala larin ibiti agbara wọn mọ si ti Ọlọrun; nitorina a ri awọn keferi bẹru awọn ẹmi buruku li abaju, bi ẹnipe ko si ipa ẹniti o to wọn igba lọwọ wọn. Nwọn gbagbọ pe awọn ẹmi wọnyi ni agbara lati gbe inu igi, tabi okuta, tabi ẹranko, tabi enia.

Ọkan ninu ọna ti nwọn wipe ẹmi buburu fi ngbe inu enia ni abiku. Li ede tiwọn, nwọn gbagbọ pe nigbati obinrin kan ba loyun, ọmọ toto ti Ọlọrun nran bọ waiye lo nkọ tete wa ninu rẹ, ṣugbọn nigbati o ba to akoko kan, ẹmi elere a wa le ọmọ toto na jade a si gba ipo, a si mu hu gbogbo iwa ti ododo ọmọ titi a o fi bi i bi enia, awọn obi na ki isi mọ bikoṣe nigbati o ba bẹrẹ si ṣe wọn ni iyonu nipa ṣiṣe aisan nigbagbogbo, tabi nipa kiku. Li aiye isisiyi, bi ẹnikan ba sa ti bimọ ku li ẹrinmeji tẹlera, nwọn o wipe elere nba a ja; awọn olorișa, ti didun-inu wọn wa ninu a ntan enia jẹ, nwọn a si yara gba eyi na mu lati won gbogbo oniruru ese jọ lati fi dẹruba awọn alaimoye.

Bi mo ba kuku wi nisisiyi pe ko si elere nibikan, ọpọ ni awọn ti yio bẹrẹ si fi eyi tabi eyini han mi, oniruru apẹrẹ ni nwọn yio si ma mu wa, niti awọn ọmọ abami to ti ṣe ohun iyanu yi tabi eyini. Ṣugbọn ohun ti mo fẹ ki ẹnikẹni ti nkawe yi mọ daju ni pe, emi ko wipe ko si ọmọ to nhuwa abami bẹ, ṣugbọn mo mọ daju, mo si wipe ko si ẹgbẹ ẹmi buburu kan nibikibi ti o ni agbara wiwa si aye li awọ enia nipa bibi ninu obinrin. Ohun kini to jẹ ki nmọ eyi ni pe, elere jẹ ọkan ninu ohun ti a nbọ ni ilẹ wa bi orișa, o si ni igbo gẹgẹ bi Oro, Eluku, ati Ifa ti ni. Emi ko wipe ko si ohun ti enia nbọ bi Oro, Ẹluku, tabi Ifa, ṣugbọn mo wipe ko si ẹmi kan nibikan to duro fun awọn orișa wọnyi. Awọn ti ngbin ẹtan kakiri nitori ijẹun tiwọn, awọn wọnyi lo da gbogbo itan oniruru wọnni silẹ, itan eyiti olukuluku ẹniti o ba gba wọn gbọ ko le ṣai ri tire fi kun wọn. Pataki ohun ti mo fẹ sọ nipe ko si ohun kan ninu abiku tabi elere to lodi si Ofin Ẹda (*Laws of Nature,*) gẹgẹ bi o ti jẹ pe ko si ohun kan ninu awọ Oro, Ẹluku, tabi Ifa to lodi tabi to yatọ si Ofin Ẹda. Ninu Ofin Ẹda wọnyi la si ti nya ọpọlọpọ sọtọ ti a si nsọ wọn di iwin tabi orișa.

ỌMỌNIDẸ.

ORI IV.

## IṢẸ.

*(Translated from "Character by Dr. Smiles").*

APA KOKANLELOGUN.

Ṣugbọn awọn eyiti o dara ju ninu awọn iṣẹ ti a fi ndaraya, ni ti iwe. Bayi ni a ri i pe bi awọn oṣiṣẹ enia ba ṣiwọ, nwọn a wa iṣẹ miran .oa fi daraya—awọn miran a gba ọna ẹkọ ijinlẹ, omiran a gba ọna ti iṣẹ ọna, awọn o pọju ni awọn ti imu ọna ti iwe. Awọn irufẹ ọna idaraya wọnyi ni o jẹ eyiti o dara julọ ti igba ni lọwọ iwa aiikan-jọpọn ati aiye ijẹkujẹ. Mo ro pe Lord Brougham ni o sọ pe. "Ibukun ni fun ọkunrin na ti o ni iṣẹ kan lọwọ eyiti o fi ndaraya!" ninu iwa ki a ṣe eyi ki a ṣe tohun ti on papa ni, ọpọlọpọ ni awọn iṣẹ ti o fi ndaraya; ki a ṣẹ ẹ lati ibi iṣẹ iwe titi de ibi ti ẹkọ nipa oju, lati ibi ti iwe itan igba kan ati iwe itan aiye enia kan lọ de ibi ti ẹkọ ọgbọn nipa igbẹin aiye gbogbo enia.

A tilẹ gbọ pe Lord Brougham ṣe iwe arofọ-itan ;.a si tun gbọ pe on ni o kọ kosi botiri itan ti 'Ọkunrin ti nbẹ ninu agogo' eyiti o jade ninu iwe 'Blackwood' ni ọdun gbọrọ ohun Sibẹ ko yẹ ki enia ṣe awọn iṣẹ idaraya wonyi laṣeju—bi bẹ kọ eyi a kuro niti onun idaraya, on ti ile arẹ lọ ti isi fun ni lokun, a si di eyiti igba okun lọwọ ẹni ti isi iko arẹ ba ni nigbati o ba kan iṣẹ pataki ti a ni ṣe.

Laisọ ti Lord Brougham, ọpọlọpọ ni awọn oṣelu ti o jẹ pe nigbati nwọn ba ṣiwọ tabi ti nwọn fi iṣẹ silẹ patapata, ni nwọn ṣe awọn iwe ti a ka kun awọn iwe pataki loni.

Laika ti Lord Brougham, ọpọlọpọ ni awọn oṣelu ti o jẹ pe nigbati nwọn ba ṣiwọ tabi ti nwon fi iṣẹ silẹ patapata ni nwọn ṣe awọn iwe ti a ka kun awọn Iwe pataki loni Bayi ni a ri i pe Iwe ti Caesar ṣe ti a npe, ni 'Caesar's Commentaries' nbẹ ninu awọn iwe ẹkọ titi di oni; iṣẹ-ọwọ ko iwe yi, lọna ti ko ru ni loju ti o si gbamuṣe, mu on ati Xenephon, ẹniti o ko iṣẹ iwe ati iṣẹ ilu pọ ṣe, dọgba.

Nigbati nwọn yo Sully, ọkunrin na, ninu iṣẹ ilu, o bẹrẹ si itan ara rẹ ikọ; o ni ero pe nigbati awọn iran ti nbọ ba ka a, nwọn yio le sọ bi on ṣe isẹ oṣelu daradara tabi on ko ṣe daradara. O si tun kọ iwe arofọ-itan, eyiti ko pari ti a si ri larin awọn iwe rẹ nigbati o ku.

Nigbati awọn ọta Turgot di tẹmbẹlẹkun ti iṣẹ ilu bọ lọwọ rẹ, o mu ti iṣẹ ẹkọ ijinlẹ ṣe. O si tun pada si ti ekọ iwe pataki eyiti o gbadun lati ilẹ wa.

Ninu awọn irin ajo rẹ, nigbati lakuyegbe arun-gun ba nfi i lapẹ loru, a ma kọ iwe orin ni ede Latin lati daraya; ṣugbọn iba eyiti a ri ninu wọnyi ni ila orin kan eyiti o ro lati fi si aworan Benjamin Franklin:

"O gba mọnamọna lọwọ Ọlọrun, o gba ọpa alade lọwọ aninilara."

"Eripuit caelo fulmen, Sceptrumque tyrannig"

Ninu awọn oṣelu ni Orance ti lọlọ yi—awọn ti o fi ti iwe ṣe'ṣẹ-ṣe bi nwọn ti fi iṣẹ ilu ṣe'ṣẹ ṣe—a le ka De Tocqueville, Thiers, Guizot, ati Lamartine; bẹni Napoleon III ko ṣe fi ọwọ rọ sẹhin ni awujọ awọn oniwe, nipa iwe ti o ṣe ti a npe ni 'Life of Caeser'

Bẹ si ni ẹkọ iwe jẹ ohun pataki ti awọn Oṣelu ti o ga ju ni England fi ngbadun ara wọn. Nigbati Pitt fi iṣẹ silẹ o fi tavọtayọ dẹhin si ẹkọ iwe Greek ati Latin, gẹgẹ bi ọgba rẹ Fox ti ṣe. Granille tilẹ ro pe ko si ẹgbẹ Pitt niti ẹkọ iwe Greek.

Nigbati Canning ati Wellesley fi iṣẹ si'ẹ, nwọn kọju mọ iṣẹ yiyi awọn iwe arofẹ orin ti Horace pada si ede gẹsi.

Bi Canning ti gbadun iwe to fi ara han ninu gbogbo iṣẹ rẹ ati ninu iwa rẹ. Opitan rẹ sọ pe, ni aṣe kan ti Pitt pe, nigbati nwọn jẹun tan ti awọn iyoku, wa nṣe faji ọrọ siso, on ati Pitt joko lapakan nwọn ngbadun iwe Greek atijọ kan. Bẹna si ni Fox Kunri mọ ẹko awọn iwe Greek, on na ka Lycophron bi ti Pitt. On ni o si tun kọ iwe kan, nipa Itan James II, ṣugbọn iwe itan na ko kun, ni gasikia, a si le sọ pe ko tẹrun.

*Translated by*

ADEYINKA AJAGBE-ỌSA

**EKO AKETE**

EKO, SATURDAY, NOVEMBER 17, 1928.

## ẸLULU T' O FA' JO

Kodede ti a fi fi ọrọ owe yi ṣe pataki ohun ti a fẹ sọ ni ọsẹ yi, nitoripe kosi alejo ti o ma gbọ orişirişi ọrọ kọrọ ti pupọ ninu awọn ara Eko nsọ ti ko ni jẹ iyalẹnu fun: nigba gbogbo ni a ma nsọ pe " Ẹnu l' Ẹbọ ": bi eyi ba ri bẹ kilo mu ki ogunlọgọ awọn ara Ilu ma fi ẹnu şepe diẹdiẹ fun ara wọn ti nwọn si rope ere ni nwọn nfi ọrọ epe na şe; şiọ! erekere ti o tun ju eyi lọ! ko si mọ: bi awọn ẹni meji jumọ njẹwọ pọ lọgan ni iwọ yio ma gbọ ti ọkan ninu awọn mejeji wọnyi yio bẹrẹ si wi fun ekeji rẹ pe " Lọ mbẹ wayi iya ti ko gbadun" "kuro lọdọ mi, iwọ alalẹ yi" tabi " sun mọ hun baba ti o gbadnn ati oniruru ọrọ ranwun rawun bẹ:

Ni ito ti ilẹ yi to loni tali le şọpe nkan nlọ dede gẹgẹbi o ti tọ ati bo ti yẹ? Ẹniti a da duro lojiji lẹnu işẹ rẹ ni yio sọpe nkan lọ dede fun on tabi onişowo ti o ti şi şabu lati arọ d' alẹ ti ko pa owo kan tabi ẹniti o fi ọpọlọpọ oşu nwa işẹ kiri ti ko ri tabi ẹniti iji aiye ti sọ di ẹdun arinlẹ tabi ẹniti atijẹ ati mu lojojumọ di işẹ onibọn fun ni yio sọpe igbadun kan daindain wa fun on: koyẹ pe bi gbogbo nkan ti ri l' Eko oni, ki a tun ma fi ẹnu wa fa ifa kufa wa si ilu nipa dida apara si ẹnikeji ẹni bi epe bi epe:

Tani ko şe iranti ọdun mẹrin ti o kọja nigbati Ọgbẹni ọdọmọkọnrin kan ku ni ilẹ yi ẹniti o jẹ pe nigbati o mbẹ ni oke epẹ orişirişi Mọto ko şe arẹ rẹ fun lilo tabi fun fifi haya; a sebi nigbati o jalaisi orin ti awọn miran nkọ ni aseko yi ni pe " bi Lamọrin ba d' ọrun ko fi Mọto ranşẹ si wọn o " a şebi ko lọjọ ko l' oşu ki enia to ma ku pẹrẹ bi igbati eşinşin ku si inu ọti ti awọn Munisiba si nfi Mọto gbe ọpọlọpọ oku lọ si Ile-ila oku ni akoko arun ekute eyiti koi ti tan ni igboro Eko titi di isisiyi: ẹ ko wa ri bi awọn ẹlomiran ti nfi ẹnu wọn pe ipekupe nipa ọrọkọrọ ti nwọn nsaba ma nsọ, bẹ ẹniti o wa iwa kuwa ni o nri iri-kuri lo difa fun apọn kan ti o fi ailobinrin lọ tọrọ ọmọ lọwọ orişa: ni ọjọ kan apọn kan dide o lọ rubọ si orişa nigbati o si şe bayi ni ẹmeji tabi mẹta, bẹni orişa ni kini apọn yi nfẹ, lọgan apọn si dahun pe, ọmọ ni o njẹ on ni iya ki orişa na ma şii dakun ki o fun on ni ọmọ: ko lọjọ ko loşu orişa yi si na ado-oyin si apọn na lara eyiti o mu ki oju rẹ şẹ funfun ti o si mu ki inu rẹ tobi ti ara rẹ si nşe fuọ fuọ nigbati o şe aisan ogun ngbo ọkọnrin apọn yi toto tẹtọ: awọn ara rẹ bẹrẹ si wo orişi arun ti o nşe yi nwọn wa ti: nigbati o şe ọkan ninu awọn ẹbi rẹ ti o jẹ alagba bere lọwọ apọn na pe, bi ki bọ orişa idile rẹ o fesi pe on ki şaibọ Obatala ti o jẹ orişa idile on: nwọn si wa bi lere pe, ti o ba mbọ kini ohun ti o ntọrọ lọwọ orişa na. O dahun pe, ọmọ ni on ma ntọrọ: nigbana ni nwọn wa sọfun pe, a ki tọrọ ọmọ ni ọna bẹ: bikoşe pe ki oluwarẹ kọkọ tọrọ aya, lẹhin na ni ki o wa tọro ọmọ; nwọn si şe itoju apọn yi titi ọ fi san ninu aisan rẹ lẹhinna ni o fẹ obinrin kan ti o si ti ipa rẹ bimọ.

Nitorina a fẹ ki awọn ti nwọn nsaba ati ma fi ọrọ bi " Iya ti ko gbadun " " Alalẹ" ba ara wọn dapara kiyesi ohun ti a kọ yi ki nwọn si dẹkun ere-egele bẹ. Ẹ jẹ ki a ma fi ẹnu pe alafia ati irọrun wa si ilu ẹ jẹ ki a si ma fi ẹnu fa owo ọpọlọpọ wa si ilu ki riroju şoju le jẹ arọwọto olukuluku wa.

---

## LEMỌMU ILU.

### LATI ỌWỌ KEKERE-AWO.

Si Oniwe Irohin *Eko Akete.*

Mo bẹrẹ f'oji,

Asọtẹlẹ lo njẹ ọrọ ana, a ti sọ fun ẹnyin Janma Içsẹ tokọja wipe pẹlu iyọnula Allah ao sọ diẹ şiun nipa işẹ Lemọmu—ilu fun ọdun mirun ti Ọlọrun şi fun un şe, nipa eyi a fi Ọpẹ nla fun Ọlọrun Ọbangiji Oni u-Ọrẹ ti O ta Lemọmu na ni Ọrẹ

ẹmi ati alafia lati igba na titi di iwoyi, nitori a koi ti fi igba kan gbo firin pe o pa Mọṣalaṣi'Jimọ jẹ—*Al-Hamdu-li-Lahi.*

Lẹhin iku Lemọmu Buraimoh ti o ṣẹlẹ l'Eko ni ọjọ kẹjidin-logun oṣu *October 1923*—ni awọn Jamat Musulumi bẹrẹsi ṣe ṣawura bi nwọn ma ti ṣe ri Lemọmu titun, ki a ma di eyi lọ wouna, nwọn ri wipe o tọ Suna loju wọn.

Nwon fi eyi si iwaju Olodumare Ẹniti O mọ enia yan nigbati awọn ẹda Rẹ ba fi aniyan rere si iwaju Rẹ.

Ṣugbọn larin gbogbo igba ti a nwi yi, ki a to mọ ẹniti yio jẹ Lemọmu, ko ṣai si ritiriti diẹ nipa elomiran ti nwọn o fẹ ki nwọn tilẹ mu, enia lọ titi ju ẹniti o ba wọ ni ifẹ okan wọn lọ, nwọn gbagbe wipe iru ifẹkufẹ bẹ ko le ṣe fa abada, bi o ba si le ṣe ẹwẹ, a jẹ wipe kosi iduro kosi ibẹrẹ bi ẹniti o gbe ọmọ ori-odo mi.

Ki ọjọ to ku ọjọ bi melo ki a ko, ni Sati ti fi apẹrẹ han awọn Jamat Musulumi pe Ligali li On yan si aye na, a si ro wipe awọn Janma ki yio ṣai sọrọ ni irẹlẹ fun awọn ẹlomiran ti o ma du'po na nigbana, gẹgẹbi ẹtọ ti o mbẹ ninu Suna.

Nigbati ọran da bẹ ki a tilẹ ni awọn Janma ṣe gẹgẹbi o ti to ti nkan fi le dara sibẹsibẹ kole tẹ awọn apakan kan, ni ero pe nwọn fẹ fi ṣe ojusaju ni, awa si ro wipe kosi ojusaju ninu ẹsin awọn Imale, gẹgẹbi a ti ngbọ o, ṣugbọn iwa aborikunkun iwa moto-moto, lo le ma mu ẹlomiran ro ero-kero bẹ.

Awọn agbalagba lo ma npa lowe, nwọn ni "Bi o ba pẹ ti nwon ti nda obi, obi a yan," nwọn po ọran yi titi bi yẹfun burẹdi, ṣugbọn nigbati o di ọjọ mọkanla oṣu *Nevember* ọdun karun (1923) ogi parada o di eko, awọn Jamat we Lawani Anabi fun Mọhammadu Ligali, larin ijo ati ayọ, titi ilẹ ọjọ na fi ṣu, bi enia gun ẹsin ninu awọn—ilu yi ko ni kọsẹ, nigbati ti kunrin tobinrin wọn njo mukumukẹ bi kokoro ti awọn bi Jari igbe Oni-waka ndanira; lọjọ yi ni on nikan ṣoṣo ti di oni Suna mẹrin pọ, on kanna njẹ Lemọmu Jamiyu, on kanna njẹ Lemọmu Agba, on kanna njẹ *Chief* Lemọmu olubori rẹ ni LEMỌMU—ILU, *La-ilaha-ila-Alaho.*

Awọn ṣebi nigbati awọn Jamat yan Ligali si ipo yi yio jẹ ohun itẹlọrun fun gbogbo wọn lati oke de ilẹ gẹgẹbi ganugunde ede ti o ti mbẹ larin ara wọn lati ilẹ, a ṣe ṣamuṣamọ, (Lawani) ti nwọn we ẹfun Lemọmu yi, bi ẹni bu ina si ẹtu ni.

Nigbati o di ọjọ bi ọjọ kẹrin tabi ọjọ karun rẹ ni awọn kan tun fi ẹnu kan wọ Mọṣalaṣi Jimọ kanna pe awọn tun fẹ fi oluwarẹ jẹ Oye Lemọmu iru kanna, lẹhin ti o jẹ wipe awọn ẹniti o ni ẹto lati fi Lemọmu jẹ Oye ni nwọn ti fi Ligali jẹ Oye ti Ọlọrun gba a ti Mọleka si gba a pẹlu.

Ẹrin pa wa lọjọ ti a ni nwọn tun jẹ Lemọmu-keji yi, nitori a ti mọ wipe iru Lemọmu bẹ ko tọ Suna lailai.

Ohun ti o dẹrin pa wa nidi Lemọmu keji na ni wipe nigbati awọn ma mu ẹgbọn Ligali ati pẹlu irufẹ agbalagba yẹn ni igba aiye rẹ lọ tẹri silẹ fun wọn we Lawani, lẹhin igba ti o jẹ wipe awọn ẹniti o nfi Oye Lemọmu jẹ, pataki bi Lemọmu Abasi Opere ẹniti o jẹ Olori awọn Lemọmu Ratibi ati awọn isangbe rẹ iyoku pẹlu awọn janma ti fi aburo rẹ jẹ iru Oye kanna lona ti o tọ Suna daradara, ti ki iṣe ọna alumọkọrọyi, aiye gbọ ọrun mọ, kosi ẹniti o ku ti o gbọ.

Nọibi gẹgẹbi a ti ngbọ ki iṣẹ oran'yan ni lati fi ẹniti a ba ti fi ṣe Nọibi jẹ Lemọmu Agba dandan, ohun iṣẹdalẹ afi ti o ba wu awọn ijọ lo ya ku, Nọibi wa fun lati ma ran Lemọmu lọwọ barato ti jaluri ba mbẹ fun Lemọmu na lati ṣe ẹsin.

Bi ko tilẹ si ọran ti ẹwọn kọ'rawọn ninu, nipa eyiti a nsọ yi sibẹsibẹ ala Kurumọ gba ni, nitoripe lai si tabi-tabi Ọga meji kole gbe inu ọkọ.

Ki a ma fi ọran gun lo titi—ọran Lemọmu koṣe Lemọmu na ko di ogun ohun ti nwọn ko ara wọn lọ si Kotu nigbati awọn apakan ti ilẹkun Mọṣalaṣi mọ apakan pe ki Adajọ ba awọn gba yẹwo nibiti ẹnikan gbe nti ilẹkun ile Ọlọrun mọ ẹnikeji ki o ma fi le ri aye ṣe ẹsin, Kotu si gba a yẹwo nwọn si da ẹbi fun awọn ẹniti o gboju gbaiya ti ilẹkun, Ọlọrun.

Lati ọjọ na lo ti han gbangba pe Oye Lemọmu Ligali ti duro bi "I" (Ai) lati ọdọ Allaha.

Lati igba ti Lemọmu yi ṣi ti mbẹ ni ipo yi, a koi ti fi igba kan gbọ wipe awọn Janma ni ikunsinu kekere kan si i, o ntọju iṣẹ rẹ daradara, o si mbu ọla ati owọ fun wọn, koi ti ṣina yẹ kuro diẹ ni ọna ti nwọn tọ si i, awọn Janma rẹ papa si nsujuda fun un, gẹgẹbi aṣiwaju wọn ati gẹgẹbi o ti to.

Ṣugbọn ju gbogbo rẹ lọ a tọrọ ẹmi gigun ati ilera ti anfani fun un, ki Sati jẹki o le mu iṣẹ rẹ de opin gẹgẹbi ifẹ awọn Ọmọ-ẹhin rẹ, ki Ọlọrun si ma ṣọ wọn lọwọ Bilisi ati Aṣitani—*Amin.*

Emi ni ti nyin nitotọ,

KEKERE-AWO.

---

PAGA! O ṢE! ABIYAMỌ KU IROJU, BURAMỌ MI ṢE BẸ O R' ỌRUN ALAKEJI AREMABỌ.

Anu ati Ojora mu ni nigbati a gbọ iku Ọdọmọkunrin wa yi ti o nsọ Ṣabu lẹba ile Ọgbẹni Geo. da Costa, (*Photographer*) ni Ricca Street, l' Eko, eyiti o ṣẹlẹ ni ọjọ *Saturday* 10/11/28 ọsẹ ti o kọja.

Ọdọmọkunrin yi jẹ enia ti o tutu ti ki si ṣe Apọn, ẹwa rẹ si dara lariu ẹbi ati ọrẹ, jẹ ẹ ni si ma ṣe ni gbogbo ọjọ aiye rẹ ; o lọ jẹ ipe Olodumare fun aisan ọjọ diẹ ti o fẹ si.

Ha ! o ṣe ! Buramọ mi lọ !
Iku da oro !
A ko tun ri Buramọ wa mọ !
Ki Ọlọrun fori jin. *Amin.*

A ki Ọgbẹni Akilusi ni Oke-Popo baba rẹ ati awọn ẹbi ati ọrẹ, wọn ku afẹku ẹni wa na o.

---

## Olusakin's Column.

### The Untimely Demise of Mrs. Caroline Ellen Taiwo Adegun (nee Bright).

**ALAS MY SISTER!**

The Angel of Death would appear to have been particularly active in claiming several victims since the beginning of the year through the medium of innumerable agencies represented by thousand and one ailments afflicting mankind in general, and the insatiable greed for cannibalism thus displayed has justified practically all the superstitious evils which the names of Leap Years have always been associated with.

What of the general depression of trade which has apparently come to stay, what of hunger and privations in several quarters, what of motor car accidents, what of political unrest at home and abroad, corruptions in high quarters, incaceration of eminent men, severity of plagues and all other factors that contribute to the sorrows and sufferings of man. These appear to be the peculiar attributes of Leap Years when, probably out of shear covetousness, February, once in four years, feels dissatisfied with the 28 days alloted to it.

Year in, year out, particularly on every watch night service, one hears not without much regret the appalling number of people who have changed time for eternity during the year, who have responded to the imperative calls of Death. To-day, those of us in the land of the living cannot but acknowledge our thanks and gratefulness to the Almighty for mercy vouchsafed to us in divers ways and on divers occasions, but nevertheless it is always good to remember that even Methusalah of old was no exception to the general law of Mortality.

In spite of its ferocity therefore, death need not be a Terror to any one under whatever guise of illness, light or serious, it may masquerade. But one cannot help shedding tears and tears and still more tears when death becomes a hell of an Insect ravaging indiscriminately the lives of young and immature folks.

Any professed christian can very well sing :—

"Around the throne of God in heaven
Thousands of children stand
Children whose sins are all forgiven
A holy, happy band,
Singing Glory, Glory, Glory !

But when it comes to the question of actually contributing ones own children to join the glorious choristers above to sing Glory, Glory, up there, the matter assumes a different aspect. That is the reason why the husband, mother, brothers, Sisters, relatives, friends neighbours, Church members of the late Mrs Caroline Ellen Taiwo Adegun rend their hearts and not their garments when the painful news of her death became a public property.

Born in Lagos at the tail end of the year of our Lord one thousand eight hundred and ninety one, of well to do parents (her father being the late E. Marmaduke Olufẹsobi Bright alias Arowoya buna, a well known and very popular figure in Lagos, during his life time.

The late Taiwo was educated at St. Paul's Breadfruit School and latterly at the Wesleyan Girls High School, where, to some extent, she distinguished herself.

Attainning the age of puberty, she was engaged to Mr. Ebenezer Adegun (Chief Clerk of the Firm of Messrs. Tangalakis & Co.,) with whom she subsequently contracted a matrimonial alliance.

Taiwo was of a very kind and unassuming disposition with cheerful countenance on now and again. A pure and innocent christian whose loyalty to her Church was unquestionable to the very last.

As a daughter she was affectionate, as a wife good not only to her object of admiration, but to all the iya Ọkọs and baba Ọkọs as well.

She took ill suddenly on Sunday, October 21st, for on the Saturday previous she was reported to be in an apparently excellent condition of health, and when the illness was getting desperately serious, it is understood their family Doctor was sent for. On arrival, the symptoms of Bubonic Plague manifest themselves to the Doctor who thereupon strongly recommended the advisability of removal to the Infectious Diseases Hospital at Ikoyi for treatment.

Accordingly, arrangement was effected whereby the deceased became a patient in the said Isolated Hospital where all cares and comfort were accorded her under the very skilful manage-

ment of Dr. I. Ladipo Oluwole, M.B., ChB., D.P.H., the Medical Officer in charge, assisted by all the male and female nurses, Mr. Adefarasin also showing maximum interest.

No sooner after her admission than some evil disposed persons started to rumour her death, some of them actually fixing time of funeral. In the meantime, the condition of the patient was giving the lie to these wicked and malicious rumours, and the deceased was showing every indication of recovery.

Her temperature which had previously been abnormally high, began to show steadily signs of abatement, and within a few days normal condition was restored. Gradually, symptoms of plague were dying out until they became totally extinct; extreme exhaustion sets in in the meantime and it was to the latter malady if it can be so called that the poor patient succumbed on Friday, the 2nd instant, ten clear days after her removal to the Hospital.

From all accounts, it would appear that the Hospital authorities did their level best, but circumstances were against them. Taiwo it is reported, having given it out about two days prior to her death, that she had already seen Christ her Saviour. Can any Christian die a more glorious and happy death?

Her remains were removed to the Wesleyan Olowogbowo Church, where Funeral Service worthy of the occasion was conducted by the Rev. Evan Williams, M.A., whose allusions to the deceased were as happy as they were complimentary.

Taiwo has come to the world and gone! she has completed her earthly pilgrimage while it was yet day. Peace be to her ashes.

Now, what useful purpose do you serve by your continued existence in the world? Are you making your life a blessing or a curse to yourself? May the blessing of God rests on each and every one of us. Amen.

Finally, we tender to the husband Mr. Adegun, to the mother, to the sister Mrs. Charlotte Mousah, to the Benjamins, the Denigas, the Dosumus, the Bifarins, the Ipaiyes, the Thomas's, the Baruwas and to all the Brights' family, our sincere condolence. ALAS MY SISTER.

---

ST. PAUL'S CHURCH BREADFRUIT ANNUAL HARVEST, 1928.

The Children Annual Harvest Thanksgiving Service of St. Paul's Church Breadfruit was held in the Church on Sunday the 28th October last, at 3.30 p.m., the Venerable Archdeacon T. A. J. Ogunbiyi, LTH, officiated. The sum of £21. 0s. 10d. was realised.

And the Adults Harvest Thanksgiving Service of the above named Church took place on Sunday the 4th November, at 3.30 p.m.

Rev. W. O. Aiyedun, B.A., preached the Harvest Sermon to a large congregation.

We congratulate the Archdeacon T. A. J. Ogunbiyi, LTH, the Pastor, for the success.

The total amount realised at the close of the service including Harvest sales was £108 0s. 10d.

---

THE ARCHBISHOP OF CANTERBURY.

**Resignation Takes Effect.**

London, Nov. 12.

The Archbishop of Canterbury's resignation of the see of Canterbury takes effect to-day. The Archbishop who is 81 years old and has been Primate for 25 years also celebrates the Golden Jubilee of his wedding to-day and the double event is to be marked by the presentation to him and Mrs. Davidson of a tribute to which thousands of people have subscribed. The presentation will be made privately this evening by the Prime Minister, and the Archbishop of York who succeeds Dr. Davidson in the primacy. The new Archbishop will be enthroned in Canterbury Cathedral next month.

---

ARCHBISHOP OF CANTERBURY'S NEW TITLE.

The retiring Archbishop of Canterbury has taken the title of Lord Davidson of Lambeth.—*Reuter.*

---

OPEN LETTERS—PERTINENT AND IMPERTINENT

To the Right Hon. Sir Wm. Joynson-Hicks,
Home Secretary.

Dear "Jix,"—I suggest that you look into the case of William Kimber, aged 69, who was sentenced at Reading the other day to three months' hard labour for stealing apples from an orchard. The sentence was so severe because it was alleged that there were 80 convictions against him. He swore he had never been in prison. The Bench disbelieved him. But since Mr. Fred Partington has just committed suicide because the police mistook him for another man, don't you think you had better investigate Kimber's case?

JOHN BLUNT.

OLUŞAKIN.

## Use Yaro for your baby!

All experienced mothers give testimony in praise of "Yaro" as an indispensable 'Preservative' for 'Babies' Yaro has no equal in suppressing those complaints which make infants feel uneasy, especially during their critical teething period. Trust Yaro for all infants' complaints and use it for your baby. Price per bottle 3/3d & 2/3d.

## Increased health for 3/- only.

"Life Tonic Tablet" imparts tone and vigour to the body, renews every atom of the flesh, prevents brain fatigue and brings indescribable comfort to all mental workers. Price 3/- per bottle.

## A chance for female sufferers.

Wireless Female Pills, the latest Scientific Discovery, have answered divers cases of functional complaints of disorders peculiar to women. These Pills serve as an effective fertiliser against barreness Give "Wireless Female Pills" a trial and prove its reliability.

Our Anti-Plague Disinfectant Fluid kills dangerous flies, bugs. cockroaches, etc., etc. 1/- and 1/6d per bottle.

## Anti-Gon Pills.

Get rid of veneareal diseases before they get rid of you by using Anti-Gon Pills—a reliable antisceptic against Gonorhea. 3/- per bottle.

WE ALSO STOCK:—

Glaxo (large and small sizes)
Vitafer—Brain Tonic
Walk Easy Anti-Rheumatic Salt 3/6 & 2/-
Pile Pills 1/6
Vibrona Wine 7/6
Lactogen
Kalzana
Effective Pile Remedy 7/6
Back and Kidney Pills 2/-
Zotal 1/6 & 2/6

*Obtainable at:—*

# IYIN OLUWA MEDICINE STORES

*Head Office*:—88, Broad Street, Lagos,
*Branches*:—6, Martins Street,
41, Alli Street, Faji Market,
27, Moloney Bridge Street
190, Griffith Street, Ebute Metta.


Disinfectant Soap of
Unrivalled Quality
Use Magnet Carbolic
Soap in your home—
it refreshes the skin
and guards against
infection. Made in
three sizes, and obtain-
able everywhere.
MAGNET
Carbolic Soap
Tablets
MAGNET SOAP
MAGNET
SOAP
WEST AFRICAN SOAP COMPANY LIMITED, APAPA.

## White's Golden Male Tonic

DOUBLE STRENGTH).

Whenver a woman has not been in the family way for a long time, the fault is usually set down to some disease or other in her generative organs.

Now while it is true that many women suffer from disease, yet many times the fault lies with the man, owing to weakness or some other disease of the male organs of generation. White's Golden Male Tonic (Double-Strength) is calculated to give full vigour to the man, and to remove all diseases which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, to cure or prevent weakness of the generative organs.

Made and sold only by VICTOR WHITE, Esq.,
*The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos.*
*N.B.*—NOT OBTAINABLE ELSEWHERE.
"Shake the Bottle."

### AREMO FUN OKUNRIN.

Nigbati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nikan ni arun wa. Şugbọn nigba pupọ ni o nję pe ara ọkunrin ni arun wa. Egbogi yi dara pupọ fun Arę, Ęda ati gbogbo arun ti ki ję ki ọkunrin şe abiamọ.

*N.B.*—O yę ki gbogbo ọkunrin ma lo igo meji-meji loşoşu—Işę ti egbogi na nşe ni ara ko şe royin.

Price TEN SHILLINGS (10s) per bottle.

*Postage 2/6 extra.*

## White's Golden Female Tonic

A splended Remedy for Female diseases such as:—Barrenness, Weakness, Paintull and Irregular, Menstruation Leucorrhœa (Whites) Cramps, Ovarian. Neuralgia, Inflammation of the Ovaries. A Tendency to Miscarriage etc, etc.

Made and sold only by VICTOR WHITE Esq.
41, Offin Road, Lagos.
*N.B:—Not obtainable elsewhere.*

### GBOGBONIŞE FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupo fun Aboyun, Iju, Ęda, Aran, Oyun ti o ba fę baję, ati orişirişi arun mi ti ki ję ki obinrin bimọ.

PRICE 10/- PER BOTTLE.
Postage 2/6 extra.

WHITE'S

## WONDERFUL BRAIN TONIC.

This medicine stimulates and rebuilds the brain in such a way, that the regular user is able to do many times the usual amount of Brainwork that he used to do, before using it. To Brainworkers and those who have examinations to pass, it is a boon.

Made and sold only by SAMUEL VICTOR WHITE, Esq.
41, OFFIN ROAD, LAGOS.
Large size 5/- per bottle. Packing and Postage 2/6 extra.
Small size. 2/6 per bottle. Packing and Postage 1/6 extra.
N.B.—*Scholars should not be without it.*

### EGBOGI ISOYE.

Egbogi yi dara pupọ fun awọn ọmọde-ile-iwe awọn ti o nfi iwe şişe ati gbogbo awọn ti o ba fę lati lọ fun idanwo.

*Iba şe ọmọde tabi agbalagba.*

## White's Golden Blood Restorer

*(A Native preparation for Women.)*

This medicine is an excellent remedy for Insufficiency or Loss of the monthly courses, Tumour in the Womb, False Pregnancy, Catarrh of the Womb, Various Runnings or Morbid Discharges from the Womb (especially those that are long-standing).

Sick Headaches, Dizziness, etc., etc.

Made and sold only by
VICTOR WHITE, ESQ, *Chemist,*
The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos.
"SHAKE THE BOTTLE".
Price TEN SHILLINGS (10/-) per bottle.
*Packing and Postage 2/6 extra, to any part of Nigeria.*

### EGBOGI ILN ĘJĘ FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun obinrin ti ko ba ri nkan oşu rę mọ (lalai to aseko), nkan obinrin ti ko ba pọ to. Aşę Ewurę pipọju, Ęda ti o ba gba, Ęyo, Oyun-koyun. Oyun ti ko ba dagba, Ęsanri ni akoko hela, Aran ati Iju.

## HORSFIELD'S

The well known suppliers of all classes of goods under the registered Trade "ZODIAC" Mark.

Call and see our Agent and give your orders to :—

MR. MOSES O. COKER,

Port Novo Market Street, Lagos.

who has samples every mail of all the latest styles of fancy and other goods, including our REGISTERED Palm Tree and Feather Embroideries.

We supply everything.

J. J. HORSFIELD & CO.,
( Manchester ) Limited,
65, George Street,
Manchester.

## GOOD MARKET.

Gonorrhea Specific, Moloke Mone, A. & D. Bula Matadi for health-restoring purposes: these Medicines are on sale at Mr. H. Campos's First Class Shop, 37, Odunlami Street, Lagos. The Specific acts like Magic : has cured many obstinate cases, and *will cure yours just the same*, if any.

Cheap Goods! Superior Quality!! Quick Fortune !!!

*Cable Address* :—"WHITE LAGOS".

MR J. T. AKIRẸMI WHITE
P.O. Box 82
20, Balogun & Breadfruit Streets
or
41, Offin Road, Lagos.

**Indents House.**

Import of General Lines
Export of Produce Commission Agencies endetaken.

Correspondence invited.

With over 22 years' experience in this line of business.

Mr. White's well-known connexion with reliable Firms in Europe is a matter of common knowledge to his clients.

A Trial is Solicited.

When replying advertisers please mention *Eko Akete*

## TO LET.

One Splendid Pleasure Car

No. L2754.

**Always at everybody's service at Tinubu Square.**

For Terms, Apply to —

A. B. Williams,
14, Bishop Street, Lagos.

## *ILE OWO OYINBO*

# JOHN RADCLIFFE

### Ni No. 63, Ehingbeti, Eko,

—— :o: ——

Ile-owo ti o wuyi fun ọja meremere bi Ṣẹda, aṣọ Yọmini ati aṣọ ti a fi ẹlẹya Oyinbo gbaleti.

Ẹ wa bẹ orişirişi ọja wa wo ni Ile-owo wa titun to kọju si Ile Niger ni No. 63, Ẹhingbẹti.

Aṣọ lorişirişi ni aṣetejọ: aṣọ Ṣẹda ati Siliki mbẹ bi aba, awọn wọnyi jẹ eyiti awọn onibara ṣa ti nwọn si ti sami si fun ra wọn. Aṣọ lami-titi ti a npe ni Ṣantọnu nkọlu 'ra wọn.

Agbalẹtu ni gbogbo ọja wa fun didara wọn.

Pọ ọ si ni owo wọn.

Pọ ọ si ni owo wọn.

Pọ ọ si ni owo wọn.